*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

### Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káárí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

# Ìkunra Ìwòsàn

*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL
~ À ń tan Ìhìnrere Káárí Aiyé

www.divineliterature.org
www.doveletters.org

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

Ìkunra Ìwòsàn

Ǹjẹ́ o mọ̀ pé Jésù Krístì gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọgbẹ́ ní ara Rẹ̀, kí àìsàn ọkàn rẹ lè rí ìwòsàn, bí? (1 Pétérù 2:24). Wọ́n nà án pẹ̀lú àwọn pàṣán tí ó ní àfọ́kù ìgò kéékèèké àti òkúta mímú, tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́, tí wọ́n ya ẹran ara Rẹ̀. Krístì yàn láti farada ìjìyà náà kí gbogbo àwa ẹ̀dá lè rí ìwòsàn sí àìsàn ọkàn wa. Àmọ́, pẹ̀lú ìrúbọ ńlá tí Ó ṣe yìí, ìwọ kò lè rí ìwòsàn gbà fún àìsàn ọkàn rẹ bí o kò bá sí ní ipò ìbátan pẹ̀lú u Rẹ̀.

Ó ṣeé ṣe ko máa béèrè pé: *Kíni Àìsàn Ọkàn?* Ẹ̀ṣẹ̀ ni àìsàn náà. Gbogbo àwa ẹ̀dá ni a bí pẹ̀lú àìsàn yìí nítorí àìgbọràn Ádámù àti Éfà (Róòmù 5:12). Bíi àwọn àìsàn mìíràn - a ó jìyà tí kò bá sí ìwòsàn fún *Àìsàn Ẹ̀ṣẹ̀*. A ó gbé ìgbésí aiyé tí ó kún fún ìbànújẹ́; a ó sì tún dojúkọ ìdájọ́ amúbíiná ìkẹyìn ti Ọlọ́run tí yóò wá pẹ̀lú òdodo. Kò sí ohun tó lè ṣèwòsàn Ẹ̀ṣẹ̀ yàtọ̀ sí Ẹ̀jẹ Jésù Krístì. Krístì nìkan ni Olúṣẹ̀gùn tí ó lè ṣe ìwòsàn àìsàn yìí; Ẹ̀jẹ Rẹ̀ sì ni Ìkunra Ìwòsàn. Yàtọ̀ sí pé Krístì ta Ẹ̀jẹ Rẹ̀ sílẹ̀ láti ṣe ìwòsàn àìsàn ọkàn wa, Ó tún mú ìrora àti ìjìyà wa kúrò (Àìsáyà 53: 4). Ó mú àwọn àbájáde Ẹ̀ṣẹ̀ Ìpilẹ̀ṣẹ̀ náà kúrò; àwọn àbájáde bíi: Àìsàn ti ara àti ti ọpọlọ tí kò níwòsàn; ìbànújẹ́ àìlópin, ìnira àìlópin, ìnilára ẹ̀mí èṣù, àti àwọn nǹkan búburú mìíràn tí a ò bá ti dojúkọ, bí kò jẹ́ pé Ó jìyà, tí ó sì kú nítorí tiwa.

Kódà, Krístì ní àṣẹ lórí gbogbo onírúurú àìsàn àti àìlera. Ọ̀pọ̀ ènìyàn ni Ó mú lára dá pẹ̀lú àwọn àṣẹ ṣókí nígbà tí ó wà lórí ilẹ̀-aiyé (Mátíù 8:16-17, Lúùkù 4:18-19, Mátíù 4:24). Bó tilẹ̀ jẹ́ pé Jésù Krístì ò sí láiyé mọ́, ní Orúkọ Rẹ̀ ni à ń rí ìwòsàn gbà láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run ní tààràtà, àti lọ́wọ́ àwọn dókítà tí wọ́n ń ṣètọ́jú ẹni. Má ṣe jìyà fún ohun tí Krístì ti jìya rẹ̀ kí o tún dojúkọ ìdájọ́ sí ìdálóró aiyéraiyé lẹ́yìn tí o ti gbé ìgbé aiyé ìbànújẹ́. Ṣe ìpinnu láti gba Krístì lónìí kí o lè rí ìwòsàn gbà!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ́ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*

Ǹjẹ́ o mọ̀ pé Jésù Krístì gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọgbẹ́ ní ara Rẹ̀, kí àìsàn ọkàn rẹ lè rí ìwòsàn, bí? (1 Pétérù 2:24). Wọ́n nà án pẹ̀lú àwọn pàṣán tí ó ní àfọ́kù ìgò kéékèèké àti òkúta mímú, tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́, tí wọ́n ya ẹran ara Rẹ̀. Krístì yàn láti farada ìjìyà náà kí gbogbo àwa ẹ̀dá lè rí ìwòsàn sí àìsàn ọkàn wa. Àmọ́, pẹ̀lú ìrúbọ ńlá tí Ó ṣe yìí, ìwọ kò lè rí ìwòsàn gbà fún àìsàn ọkàn rẹ bí o kò bá sí ní ipò ìbátan pẹ̀lú u Rẹ̀.

Ó ṣeé ṣe ko máa béèrè pé: *Kíni Àìsàn Ọkàn?* Ẹ̀ṣẹ̀ ni àìsàn náà. Gbogbo àwa ẹ̀dá ni a bí pẹ̀lú àìsàn yìí nítorí àìgbọràn Ádámù àti Éfà (Róòmù 5:12). Bíi àwọn àìsàn mìíràn - a ó jìyà tí kò bá sí ìwòsàn fún *Àìsàn Ẹ̀ṣẹ̀*. A ó gbé ìgbésí aiyé tí ó kún fún ìbànújẹ́; a ó sì tún dojúkọ ìdájọ́ amúbíiná ìkẹyìn ti Ọlọ́run tí yóò wá pẹ̀lú òdodo. Kò sí ohun tó lè ṣèwòsàn Ẹ̀ṣẹ̀ yàtọ̀ sí Ẹ̀jẹ Jésù Krístì. Krístì nìkan ni Olúṣẹ̀gùn tí ó lè ṣe ìwòsàn àìsàn yìí; Ẹ̀jẹ Rẹ̀ sì ni Ìkunra Ìwòsàn. Yàtọ̀ sí pé Krístì ta Ẹ̀jẹ Rẹ̀ sílẹ̀ láti ṣe ìwòsàn àìsàn ọkàn wa, Ó tún mú ìrora àti ìjìyà wa kúrò (Àìsáyà 53: 4). Ó mú àwọn àbájáde Ẹ̀ṣẹ̀ Ìpilẹ̀ṣẹ̀ náà kúrò; àwọn àbájáde bíi: Àìsàn ti ara àti ti ọpọlọ tí kò níwòsàn; ìbànújẹ́ àìlópin, ìnira àìlópin, ìnilára ẹ̀mí èṣù, àti àwọn nǹkan búburú mìíràn tí a ò bá ti dojúkọ, bí kò jẹ́ pé Ó jìyà, tí ó sì kú nítorí tiwa.

Kódà, Krístì ní àṣẹ lórí gbogbo onírúurú àìsàn àti àìlera. Ọ̀pọ̀ ènìyàn ni Ó mú lára dá pẹ̀lú àwọn àṣẹ ṣókí nígbà tí ó wà lórí ilẹ̀-aiyé (Mátíù 8:16-17, Lúùkù 4:18-19, Mátíù 4:24). Bó tilẹ̀ jẹ́ pé Jésù Krístì ò sí láiyé mọ́, ní Orúkọ Rẹ̀ ni à ń rí ìwòsàn gbà láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run ní tààràtà, àti lọ́wọ́ àwọn dókítà tí wọ́n ń ṣètọ́jú ẹni. Má ṣe jìyà fún ohun tí Krístì ti jìya rẹ̀ kí o tún dojúkọ ìdájọ́ sí ìdálóró aiyéraiyé lẹ́yìn tí o ti gbé ìgbé aiyé ìbànújẹ́. Ṣe ìpinnu láti gba Krístì lónìí kí o lè rí ìwòsàn gbà!

Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ́ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*